## Tani Ìwé pélébé yí wà fún?

Ìwé pélébe yìí ńṣe ìrànwọ́ àti ìmọ̀ràn fún àwọn ènìyàn tí ó rò pé àwon lè ṣàbámọ̀ ìmúniṣòwò ní UK.

## Kíni ìmúnisòwò?

ìmúniṣòwò jẹ ìwà ọ̀daràn tó buru. A ń fènìyàn ṣòwò nígbà tí àwọn míràn bá mú wọn (tàbí mú yíká) wa orílè èdè kan nípa ìdúnkokò móni, dérúbà, pa lára tàbí fipá mú won láti ṣiṣẹ́ tàbi ohun míràn tí wọ́n kò nífẹ̀ láti ṣe.

## Bí a bá tọ́ka rẹ bí ẹni a fipá mú sòwò, nígbà náà wá lẹ́tọ̀ sí:

- Ìrànwọ́ àti ààbò láti ọ̀dọ̀ Ìjọba Uk (èyí ni a ńpè ni National Referral  Mechanism). Gbogbo ìrànwọ́ ni a pèsè lábẹ́ ìfọ̀kàntán.
- Àtìlẹ̀hìn bí ó bá pinnu láti bá ọlọ́pà sọ̀rọ̀

**National Referral Mechanism** náà ni a ti fi sí ipò láti ṣèdámọ̀ àwọn olùṣàbámọ̀ ìfípámúniṣòwò kí a sì mú wọn lọ àwọn ilé iṣẹ́ tí yóò ṣe ìrànwọ́ àti àtìlẹ̀hìn.

Olúkálukú tí a tọ́kasí gẹ́gẹ́bí olùṣàbámọ̀ ìfípámúniṣòwò ló lẹ́tọsí ìgbàpadà díẹ̀ àti ìfiyèsí lákókò ọjọ́ márundínlọ́gọ́ta. Àwọn wọ̀nyíì ni àwọn ilé iṣẹ́ wọ̀nyíì pèsè èyí tí ó dá lórí ibi tí ẹni náà wà ní àkókò yìí:

- The Salvation Army (England àti Wales)
- Tara àti Migrant Help (Scotland)
- Migrant Help (Northern Ireland).

## O lẹ́tọ̀ láti

Ẹ̀rù lé bà ọ́, àìlágbára tàbí dáwà. Síbẹ̀síbẹ̀, ìrànwọ́ wà o sì lẹ́tọ̀ àti yíyàn. O lẹ́tọ̀ láti:

- Dídání ìmí-ẹ̀dùn, egbògi àti àtìlẹ̀hìn afòjúrí.
  - wíwá ìbùgbé ààbò ìgbà díẹ̀ fún ọ
  - ṣíṣe ìrànwọ́ ìtojú egbọ̀gi fún ọ
  - wíwá ẹnìkan láti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti farada ìrírí rẹ
  - ìpèsè ògbùfọ̀/agbédègbẹyọ̀ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti sọ̀rọ̀ ní Gẹ̀ẹ́sì
- ààbò: ìmúniṣòwò jẹ́ ìwà ọ̀daràn. Bí ó bá pinnu láti fisun ọlọ́pà wọ́n gbọ́dọ̀ dá ọ lóhùn.
- Ìmọ̀ràn òfin aládàni.

O lè gba ìmọ̀ràn láti ọ̀dọ̀ olùmọ̀ràn amòfin rẹ tàbí Ilé iṣẹ́ Agbara Ìlú Lámọ̀ràn nípa ìdápadà tí o lè rí gbà. Bí o bá ní àtìléhìn òṣìṣé, wón lè ràn ó lówó láti gba ìmòràn.

Àwọn tí kìí ṣe ọmọ ìlú Bíritíṣì tàbí Agbègbè Ìṣunná Úròpù ni a kòní mú kúrò ní Uk lákòkò ìrígbàpadà àti ìrònú. Bí a bá dá o mo gégébi aṣàbámọ̀ ìmúniṣòwò, alè fún ọ ní ìwé ìgbélù fún ìgbà díẹ̀.

Bí o kò bájẹ́ Bírítíṣì tàbí Agbègbè Ìṣunná Úròpù (tí o kòsì lẹ́tọ̀ láti wà ní UK) nígbà náà laó ràn ọ́ lọ́wọ́ láti padà sí ìlu rẹ, bí kòbásí ewu láti ṣe bẹ́ẹ̀.

## Kíni ohun tí yóò ṣẹlẹ bí mo bá pinnu láti sọ ìrirí mi fún ọlọpa?

Ọlọpa yóò:

- Bá ọ sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ó ṣẹlẹ̀
- Fún ọ ní ààbò lọ́wọ àwọn tó lè pa ọ lára
- Bẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìwádìí
- Ṣe ìwifún fún ọ.

## Fún ìrànwọ àti àtìlẹhìn

**England àti Wales:**
The Salvation Army Human Trafficking Helpline
☎ 0300 3038151

**Northern Ireland àti Scotland:**
Migrant Help
☎ 07766 668781

**Scotland:**
TARA
☎ 0141 276 7724

**Ọlọ́pa:**
☎ 999

HMG-VHT-DL-E-(0913)-Yoruba

HM Government

# Ìrànwọ́ fún àgbàlágbà tí ó ṣàbámò ìmúniṣòwò

**Àwon ẹ̀tọ́ rẹ tí ó wa ní ìmúniṣòwò ìfiyàjẹni ní UK.**



**Fún ìrànwọ àti àtìlẹhìn**
**The Salvation Army**
**0300 303 8151**